# Bibeli fun awon omode

# Nigbati Olorun da ohun gbogbo




Ikosile gba owo: Edward Hughes

Ayaworan: Byron Unger; Lazarus

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Olu'lo: Bob Davies; Tammy S.


Itan 1 ti 60


**www.M1914.org**

***Bible for Children,*** *PO Box 3, Winnipeg, MB R3C 2G1 Canada*



Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi, niwon igba ti o ko so di owo.


Èdè Yorùbá

Yoruba

Tani oseda wa? Bibeli, oro Olorun, so bi iran eniyan se bere. Latetekose, Olorun da okunrin akoko osi pe oruko re ni Adamu. Olorun da Adamu lati inu erupe ile. Nigbati Olorun mi emi iye sinu Adamu, odi alaye. Ori ara re ninu ogba didara kan ti ape ni Edeni.



1

Ki Olorun t'oda Adamu, oda Ile aiye tokun fun ohun meremere. Leselese Olorun da awon oke ati awon ile tokun fun ewe, fulawa oloorun didun ati awon igi nla, awon eiye alawo didara ati awon kokoro oyin, eja nla inu okun ati awon igbin.



Lotito, Olorun da ohun gbogbo toye.

2

Ni ibere ohungbogbo, ki Olorun toda ohunkohun, kosi ohun kan afi Olorun. Kosi Imole tabi okunkun. Kosi oke kosi ile. Kosi ana kosi ola. Olorun tiko ni ibere nikan lowa. Olorun sib ere ise. Latetekose, Olorun da awon orun ati aiye.





Aiye siwa ni juujuu osi sofo. Okunkun siwa loju ibu. Olorun si wipe “Jeki imole wa”.





Imole siwa. Olorun pe imole ni ojo ati okunkun ni oru. Ati Asale ati owuro ni ojo akoko.





Ni ojo keji, Olorun mu awon omi osa, omi okun ati omi adagun bo si ipo won labe orun. Ni ojo keta, Olorun wipe, “Jeki Ile kofi ara han”. Osi ri be.





Olorun p’ase wipe ki koriko ati ewebe ati igi ati igi eleso farahan. Won si farahan. Ati asale ati owuro ni ojo keta.





Olorun da oorun, ati osupa, ati awon irawo oju orun ti enikan kolee ka. Ati asale ati owuro, ni ojo kerin.



Awon eda inu omi ati eja ati eiye ni Olorun da. Ni ojo karun Olorun da eja nla ati kekere, eiye olorungigun ati eiye kekeke. Olorun da oniruru eja lati kun inu omi ati oniruru eiye lati gbadun ile, ati okun ati ofurufu. Ati asale ati owuro ni ojo Karun.



9

Lehin eyi, Olorun tun wipe "Jeki ile mu oniruru eda alaye jade …" Oniruru eranko ati kokoro, ati eranko ti nrako si jade wa. Awon erin nlanla ati eran igbe. Awon obo ati oni ti nrako. Awon ekolo ati eran igbe. Awon Ologbo ati oniruru eranko igbe ni Olorun da l'ojo na.

Ati asale ati owuro ni ojo kefa.



10

Olorun se ohun miran ni ojo kefa – Ohun ti o se pataki. Ohun gbogbo ti wa n'le fun eniyan. Ounje wa ni oko ati awon eranko ti yio sin. Olorun si so wipe, "Jeki ada eniyan li aworan ara wa. Jeki oje oluwa lori lori oungbogbo ti o wa ni ile." OLORUN DA ENIYAN NI AWORAN RE; NI AWORAN RE L'ODA ENIYAN …



11

Olorun wifun Adamu pe. "Je ohungbogbo ninu ogba. Sugbon mase je eso imo rere ati ibi. Bi o ba je ninu re iwo yio ku."



12

OLUWA Olorun si wipe, "Ko dara ki okunrin ki owa nikan. Emi yio se oluranlowo fun." Olorun mu eiye ati eranko wa si odo Adamu. Adamu fi oruko fun gbogbo won. O gbodo ni laakaye lati se eyi. Sugbon laarin awon eiye ati eranko kosi eniti o to lati je iyawo fun Adamu.



13

Olorun fi orun ijika kun Adamu. Omu okan ninu iha re, Olorun da Obirin lati inu iha Adamu. Obirin ti Olorun da ni iyawo fun Adamu.



14

Olorun da ohun gbogbo ni ojo mefa.
Olorun si bukun ojo keje osi pe ni ojo isimi.
Ninu ogba edeni, Adamu ati Efa aya re
ngbe ninu ayo nla, won ngboran si Olorun.
Olorun je OLUWA won, olupese
fun won ati ore won.





Nigbati Olorun da ohun gbogbo

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Genesisi ori kini si ekeji

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese.
Iku ni ere ese.

Olorun feran wa tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Nisiyi Olorun le dari ese jiwa.

Bi o ba fe yi pada kuro ninu ese re, so fun Olorun bayi wipe: Olorun mi owon, Mo gbagbo wipe Jesu ku fun mi osi ye. Jowo wa sinu aye mi ki o si dari ese mi jimi, ki emi bale ni aye otun nisisiyi, kiisi ba o gbe titi lailai. Ranmilowo lati gbe igbe aye mi fun o gegebi omo re. Amin. Johannu ori keta ese kerindinlogun.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!